

# Ẹkáàbọ̀

## Sílé ìwòsàn yìí

## Gẹ́gẹ́ bíi álejò o wa, ẹ ní ẹ̀tọ́ sí àwọn ǹkan wọ̀nyí:

| | |
|---|---|
| **Iyì** | - Ani ìlati bu ọla, iyi àti ọ̀wọ̀ fun yín |
| **Mọ̀** | - Orukọ àwọn òsìṣẹ́ tó ń dayín lohùn, lati kọ́ nípa ìlànà yíyan ètò ìlera ìbísí (ìbímọ) tí ẹ bá fẹ́; àti láti dáhùn gbogbo ìbéèrè yín lótìítọ́ àti lódodo |
| **Ẹ ní Ànfàní** | - Láti rí àmójútó tó yẹ, láì sí ẹ̀yàmẹ́yà, tàbí ojúsàájú irú èyíówù kójẹ́ (ẹ̀yà, èdè, ọjọ́ orí, ọkùnrin àbí obìnrin, ipò ẹni lábẹ́ òfin àti l'áwùjọ, ohun ìní, tàbí irú àwọn òsùnwọ̀n míràn bẹ́ẹ̀) |
| **Yíyàn** | - Lati yàn fúnraa yín bóyá ẹ fẹ́ bímọ, bóyá ẹ fẹ́ f'ètò sí ọmọ bíbí, àti ìlànà ìf'ètò sí ọmọ bíbí tí ẹ fẹ́. Láti yan ètò ìlànà tó wù yín. Àti láti yí ọkàn yín padà, kí ẹ sì yan ètò tí ó bá wù yín |
| **Àábò wáà** | - Láti le s'ètò ìf'ètò sí ọmọ bíbí tí ó yẹ tí ó sì mú'ná dóko, tí kò sì léwu |
| **Ibi Ìpamọ́** | - Láti gba ìyànjú níbi tí ẹnikẹ́ni kò ti ní gbọ́ tàbí dási |
| **Ìfọkàntánni** | - Láti mọ̀ dájú pé gbogbo ohun tí ẹ bá sọ fún wa, etí kẹta kò níí gbọ́ |
| **Ìrọ̀rùn** | - Ẹ ní ẹ̀tọ́ láti wà ní ipò ìrọ̀rùn |
| **Títí lọ** | - Láti máa gba ètò ìlera àti àwọn ǹkan tó yẹ níwọ̀n ìgbà tí ẹ bá nílò wọn |
| **Èrò** | - Ànfàní wà láti sọ èrò ọkàn yín nípa ìtọ́jú ti ẹ gbà. |

## *Ẹ lè ràn wá lọ́wọ́ láti rí ìtọ́jú tó péye gbà bí ẹ bá:*

- **Ṣe àlàyé ǹkan tí ẹ fẹ́** fínífíní.
- **Béèrè àlàyé** lórí ohun tí ẹ fẹ, kí ẹsì rii dájú pé óye yín yékéyéké. Ẹ lè se àròtẹ́lẹ̀ àwọn ìbéèrè tí ẹ fẹ́ bèèrè.
- **Ṣe àlàyé lotitọ ati lódodo gbogbo itan ìlera yín**, pẹlu ìyípadà nípa ìlera yín.
- **Ẹ tẹ̀lé ìlànà gbogbo.**

**Tí ẹ bá ní ìbéèrè, ẹ jọ̀wọ́ ẹ béèrè**

**Tí ẹ bá ní ìṣoro, ẹ jọ̀wọ́ ẹ sọ̀rọ̀ síta**

**Tí inu yín bá dùn si itoju ti ẹ ri gba, ẹ jọ̀wọ́ ẹ rẹrin músẹ́, ki ẹ si dúpẹ́ lọ́wọ́ àwọn olùtọ́jú yín**

Get it together
KNOW. TALK. GO.

NURHI 2
NIGERIAN URBAN REPRODUCTIVE HEALTH INITIATIVE